# “Ẹ ma bu àwọn òkú; torí pé wọn lọ ba nǹkan ti wọn ti síwájú”

Láti ọ̀dọ̀ Aishah- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pé: Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ẹ ma bu àwọn òkú; torí pé wọn lọ ba nǹkan ti wọn ti síwájú”
[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe ki a ma maa bú àwọn òkú, ati pe eyi wa ninu awọn iwa buruku; torí pé wọn ti de ibi ti nǹkan ti wọn ti síwájú wa ninu iṣẹ rere tabi buruku, gẹgẹ bi o ṣe jẹ́ pé èébú yii ko lee dé ọdọ wọn, o kan maa kó sùtá ba àwọn alàáyè ni.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5364